The Chief Secty Government

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. II. No. 73. SATURDAY, DEC. 1, 1923. FOURPENCE

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"**Specialities:** Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads etc., etc., etc."

Ọgbẹni DURO THOMAS

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şẹşẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

**N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.**

***J. F. SICK*** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laikai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Qja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Qja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ẹkole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorișirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onișowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po ọ.

---

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

Cotton.
Sundries.
Hardware.
Provisions.

27, Koseh Street, Lagos.

**THE LAGOS HOT**

Iced Drinks of every d
cription on sale at the ab
popular Hotel.

Clients' comfort occupie
prominent part in our p
gramme.

Billiards, an attraction.

TERMS :—**Strictly Cash.**

H. H. Kin
*Propriet*

---

# OJA OPO MBE

NI ILE EGBOGI NLA TI FILIPI TI A NPE NI

**Phillips' Medicine Store**

ni Ajẹlẹ, Ita Faji, Ita Balogun, ati ni Ebute Mẹta (17 Ibadan Street.)

A nta ọpọlọpọ Egbogi iyebiye eyiti awọn enia ko mọ tẹlẹ ri, ati awọn miran ti ow
jẹ egbogi titun ni ọpọ lati ba jẹ ki awọn onibara wa mọ wọn.

Oriși awọn Egbogi na pọ ju eyiti a le ma kọ silẹ ninu iwe yi, bẹni ẹdin owo on w
si pọ to, sa wa wo wọn.

Lẹhin *Christmas* (Keresimesi) owo awọn Egbogi na yio pada bọ si ipo w
Nitorina, ma jafara.

Ọpọlọpọ Egbogi miran ti o ti mọ ni ŏ si ri ra ni ọpọ pẹlu.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

ỌRỌ ỌMỌ IYA KO RI BẸ.

A gbọ pe o jẹ aṣa lati iwọn oṣu bi mẹfa sẹhin fun awọn Alufa Ijọ C M.S. lati ma ṣe ipade pẹlu awọn Alufa Ijọ *Wesley* lẹkan loṣoṣu a si sọpe a ṣe ipade ti oṣu yi ni Ile Alufa Ijọ Onidunkun Oyinbo. O to ọdun diẹ sẹhin nisinsinyi ti awọn Ijọ mejeji wọnyi ti sowọpọ a si ro pe nwọn gba Ijọ Alaribọmi ( *Baptist* ) si pẹlu. Irufẹ Idapọ bayi ko le wun awọn Ijọ wọnyi nitoripe Oyinbo lo da ekinni, ekeji, ati Ẹkẹta silẹ nilu wọn ki nwọn to mu wa silẹ yi ; Gbongbo Ijọ Ekini ati ti Ekeji wa lati *England* Gbongbo Ẹkẹta si wa lati *America* ; nigbati a si ri awọn Ijọ Ọmọ Ibilẹ Enia dudu ti nwọn npapọ bayi nibi, njẹ o ṣe gẹgẹ niyẹn. Bi Oṣupa ba ntanna Irawọ yio si ma tan tirẹ bakanna ti ko pada,

A Ṣ'EYI Ṣ'AMỌDUN O.

Awọn Ijọ *Bethel* ati awọn ti *Salem* ṣe Ajọdun Kejilelogun wọn ninu ọsẹ yi ; ọpọlọpọ Alufa wọn lo de lati Ibiṣẹ wọn nidalẹ fun Ajọdun yi. Orişirişi ipade t'ọkọnrin, t'obinrin, t'ọmọde ati t'agba ni a ṣe. Bẹ̄bẹ̄ ni ka ma ri.

LỌWỌ ATẸHINKU GBOGBO.
OLUWA RERE GBA WA !

Lati Ilu awọn Déwò ( *Port Harcourt* ) ihin kan ni pe ojo aragbabu kan rọ ni ọjọ 19 oṣu *November* to kọja ti o mu ki agbara ma ṣan yaya ni oju agbara ni opopo ode bi odo nla tobẹ ti o fi gbe ọmọde kan ọmọ ọlọdun marun lọ bambam : ijọkeji ni a gbọ pe nwọn to ri oku ọmọ na ni odo Okrika nibiti agbara gbă lọ. Yio jẹ ohun ti o dara ti D.O. Ilu yi ba ṣe ayan lati paṣẹ ki a bo oju agbara Ilu na ti yio jẹ ailewu fun awọn enia ibẹ. A ba awọn obi ọmọ na daro atẹhinku yi.

ARẸ MU Ọ, AIYE SU Ọ,
LALA PỌ FUN Ọ ?

Bẹ si ni a gbọ pe Oyinbo kan ninu ọkọ *Zaria* pa ara rẹ sinu ọkọ na nipa fifi ọbẹ yun ara rẹ lọrun bi ẹran ki ọkọ na to gunlẹ si ( *Port Harcourt* ) ni ọjọ 18 oṣu to kọja na. Eyi kele o.

Ẹ KU IYANJU.

Awọn ọmọ Ile-iwe diẹ nṣe Idanwo wọn ti *Oxford* ninu Gbangan Ile-iwe Giga ti Eko l'ọsẹ yi. Ọwọ nyin a ran o !

ỌLA NGORI ỌLA. IYẸN WU WA O !

Ninu Iwe Irohin Saro, *Sierra Leone Weekly News*, ti ọjọ 17 oṣu *November* to kọja ni a ri ka pe a fi Ọlọla Ọgbẹni Claudius May J.P. Oniwe Irohin na jọ Olori ( *Mayor* ) "Munisipa" ti Saro fun ọdun 1923—1924. Ẹnyin ọkawe wa yio niran pe ko ju iwọn ọdun kan-abọ tabi meji lọ ti Ijọba Saro yan Ọgbẹni Onifẹ Ilu rẹ yi si Ajọ Igbimọ Aṣofin ti Ilu Saro eyiti o si mu ki a ma fi Ọlọla si pipe orukọ rẹ. O kare, Saro Owẹnga, ọmọ onibu ẹja !

O DABỌ O.

Ọgbẹni J. Egerton Shyngle ọlọla da kan lọ si Abẹokuta ni *Wednesday* Ọsẹ yi fun ẹjọ kan nibẹ lẹhin igbati o bọ de lati Ibadan lọjọ na gan, Ọgbẹni ọlọla yi ati Ọgbẹni J. Oluwọle George ati Ọgbẹni Alli Johnson ti Ibadan lo jọ wọ "Mọto" kanna pọ lọ si ibiti a wi yi.

## IPADE NBỌ.

Ipade gbogbo-gbo ti Ẹgbẹ Tunluṣe nbọ lọsan yi ni 'le Afari-Ogun ni agogo mẹrin. Ọrọ pataki ti a o sọ nibẹ pin si ọna mẹta. Ẹnyin Ọmọ Ẹgbẹ, afara kosi o ! K' ẹsẹ pe perepere.

## ELA LỌRỌ

Lilọ ti *Bishop* Howells nlọ si Abẹokuta ninu ọsẹ yi, kiṣe lati lọ "yi Ẹgbẹ Iya pada" gẹgẹbi ẹlomiran ti le ṣi ro. Ẹ fi eyi sọkan o !

## ỌRỌ ELEKO TUN SỌJI !!!

Ọgbẹni C. Ọlayẹmi Blaize ṣẹṣẹ ṣe Iwe kan nipa ọrọ Eleko ti a nta ni Office wa ni Sisi (6d)

O kuṣẹ, ara Igbore, ọmọ R. B. B. Ọlamilẹgẹ, A-fowo-gbe'ṣẹ Oluwa.

---

## NIGBAWO NI APO ẸKUN DI IKA'LA SI ỌMỌ TITUN ?

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo juba o,

Bi enia nṣiṣẹ aṣekara lojojumọ laisimi, ti ko si jẹ ẹniti o nda'raya lẹkọọkan, lẹhin ọdun diẹ, lẹhin igba diẹ, ao kojọ pẹlu awọn to sun s'iboji, labẹ kaju n'Ikoyi. Bi ẹnikan ba si wipe iṣẹ ere nikan ni on mọ ṣe laibikita fun iṣẹ, alantankan yio ta'kun sinu iṣasun rẹ, bẹni iyatọ ko si larin ọna ọfun ati ọna ọrun.

Orişirişi iṣẹ lo wa, orişirişi ere lo si wa pẹlu ṣugbọn atiro to ni on fẹ gun agere yio ri ẹrẹkẹ ara rẹ lai-gbe-jigi; biositiwu ki iṣẹ ewurẹ pọ to fun iṣẹ şişe, ko gbọdọ daba lati gbe gari ẹṣin ru. Njẹ bi ẹranko ba mọ ohun to tọ ati eyiti ko tọ lati ṣe, melomelo lo ba yẹ fun olukuluku enia lati mọ ipo ara rẹ ?

Ọpọlọpọ enia nilẹ yi lo dabi atiro to fẹ gun agere, eyiti awọn *Mammy* oniyẹri melo kan si ṣe nilọlọyi kun ajadi aperẹ Nigbati nwọn jẹ, ti nwọn yo tan, nwọn ṣa ara wọn jọ nijọ Kẹrindilogun oṣu to kọja, *October 16*, nwọn ni bi nkan ti nlọ si n'ilu ko tẹwọn lọrun, nwọn ... pinnu lati fi iwe ranṣẹ si Gomina bẹ gẹgẹ... Lẹhin ipade yi nwọn ṣe wosika na, nwọn fi ... ranṣẹ si Ọgbẹni Henry Carr, balẹ ilu, ẹniti o ... si fi ṣọwọ si Gomina gẹgẹ bi ilana ati iṣẹ awọn ... ti o kọ ọ.

Ogun (20) obinrin lo f'ọwọ si iwe alaa... nla yi—a ko si ni ọta kanṣoṣo ninu won ; ṣugbọ... bi nwọn ti pe ara wọn ni Aṣoju gbogbo obinrin... Eko, ti nwọn si wipe iṣẹ ti gbogbo obinrin... Eko ran wọn ni awọn jẹ sinu iwe na nigba... a mọ daju gbangba pe ọrọ ko ri bẹ, ati p... fuja lasan ni nwọn nṣe, o tọ, o si yẹ jọjọ k... a sọ diẹ ninu ohun ti a mọ nipa awọn to k... iwe yi ati ohun ti nwọn kọ sibẹ laisi aranka... tabi ojusaju.

Ninu aroye ti nwọn ṣe sibẹ nipe :—"T... *women both educated and uneducated find th... there is hardly any provision made for the... employment whereby they can earn their livelihood. All the Government offices are closed to them ... x with the exception of the Hospital, Prison and Asylum* ;"—itumọ eyi nipe Ijọba ko ba obinrin... wa iṣẹ ṣe nibi iṣẹ Ọba—bikoṣe iṣẹ Ile Alarun, ti Ọgba Ẹwọn ati ti Yaba.

Nwọn si tun wipe Ijọba ko kọ ile giga fun awọn ọdọmọbirin ilu. Lẹhinna, nwọn damọran pe ki Ijọba da owo ọti duro ati orin ti awọn kasi ikọ-ku-kọ nilu ati iwa agbere (*prostitution*), ati isọkusọ ti awọn rope iwe irohin nsọ l'Eko eyiti nwọn pe ninu iwe wọn ti a nsọro r... yi ni "*Newspaper pernicigns literature.*"

Ki a to bẹrẹsi yẹ diẹ ninu ọrọ awọn *Mammy* yi wo lẹsẹsẹ, a tọrọ gafara lati bere lọwọ Mrs. C. Ọlajumọke Obasa alakoso wọn pe nibo ni nwọn gbe ṣe ipade wọn, obinrin melo lo wa nibẹ, ati pe tani si fi awọn ogun (20) obinrin to fọwọ s'iwe na joye Aṣoju gbogbo obinrin Eko. Nibo ni Erelu wa, nibo ni awọn Olori Ọba wa, nibo ni awọn Iyawo Oloye-onila-funfun wa, nibo ni Bella aya Loya Moore wa, nibo ni aya Dokita Jones wa, nibo ni Simons onile nla aya Baba Adini wa, nibo ni Rekiatu Ọgabi-Ọbanikoro wa, nibo ni Layide ọmọ Taiwo olowo wa, nibo ni Sẹlia olobi iya ẹgbẹ Ebute-Awo wa, nibo ni Amina iya Afa Tijani ti ila onibaba wa, nibo ni Ṣẹfi ọmọ Shitta Bey wa, nibo ni Barikisu Durojaiye Dabiri wa, nibo ni Rabi alaṣọ Iyalode ilu ọmọ sodẹ wa, nibo ni iyawo Henry Carr papa wa, nibo ni aya Mojola Agbebi ologbe wa, nibo ni iya Sinọbu Anin... aya Buraimọ Arowolo wa, ani nibo ni Jariogbe oniwaka ati awọn jakanjakan obinrin miran wa pẹlu ti irufẹ diẹ ninu awọn to kọwe si Gomina yẹn ni awọn ni Aṣoju gbogbo obinrin Eko?

Laisi ani ani, enia pataki wa ninu awọn *Mammy* nwọnyi, ṣugbọn ẹlomiran ninu wọn dabi igbati a gbe gari silẹ t'ewurẹ yọju.

Nigbati nwọn tilẹ nkun wipe obirin ko ri iṣẹ ṣe nibi iṣẹ Ọba, ṣe nwọn fẹ ki a da ọkọnrin duro nitori wọn ni—nigbati o jẹ pe iṣẹ ko iti kari ọkọnrin papa. Ko da mi loju bi awọn *Mammy* oniyẹri yi mọna Imuṣin, Oyigbo, Agege Alagbado, Ejinrin, Ikorodu ati ibo miran ti nwọn le ma lọ ṣowo Epo, Iṣu, Ata, Iyọ, Ilẹkẹ tabi lati ma ta Mọinmọin, Abala, Ekuru, Ọjọjọ, tabi ki nwọn ma ro Elubọ, Fufu, ati ọka ta tabi iṣẹ Alagbafọ—iyẹn to ba jẹ otitọ ni nwọn fẹ ṣiṣẹ. Boya nwọn si rope awọn bẹta ( *bettler* ) ju ẹniti o le ṣe iru iṣẹ ti a ka silẹ nwọnyi lọ nitori ibọsẹ ṣẹda wọn ( *silk stocking* ) ati akisa oyinbo ti nwọn nko ro 'ra lojojumọ.

Owo ọti ! Nwọn ni ki Ijọba da owo ọti duro, bẹni ṣaṣa ni ẹniti ọkọ rẹ ko mọ ọti mu ninu wọn boya a tilẹ le ri diẹ ninu awọn obinrin na papa ti a ko le fe ọti kun ninu egbogi iju to nlo. He la nwo ka to s'ọmọ l'orukọ.

Nwọn tun f'ẹnu kan ọrọ agbere ( *prostitution* ) Eyi ara ! A ko pe ẹnikẹni ni panṣaga ninu awọn *Mammy* yi o, Ekute ha le mu 'je ogiri ki o ye ? Ṣugbọn ta lo mọ ? A si mọ eyiti ọkọ rẹ wa ni gusu ti on papa wa ni gabasi; lai ka ẹyiti ọkọ rẹ gbeyawo tan ti o tun ko obinrin jọ. Tani le jiyan pe ijọba ko sa ipa to lati jẹ awọn agbere obinrin niya, nigbati ọlọpa ko yẹ mu awọn obinrin Ijọ ati Isobo to nrin irin werewere l'ẹsẹ ? Ṣugbọn awọn kuẹkuẹ nikan kọ lo nṣ'agbere, igbapupọ ha kọ ni awọn enia ti wa na nf'oru b'oju ti nwọn si unokun l'ọgbẹlẹ, tabi ọpọlọpọ obinrin tiwa kọ ni obinrin ẹgbẹ wọn ti yọ kuro nile ọkọ wọn ?

Eyiti nwọn sọ nipa ile ẹkọ giga f'obirin, ati pe Ijọba ko nani ati la awọn ara wa to wa l'okunkun loju pa mi lẹrin pupọ. Agbọ ti awọn makunu ati talaka Ọlọrun to wa ninu awọn *Mammy* oniwe yi, ṣugbọn awọn iyoku bi mẹta tabi mẹrin to lowo Iọwọ diẹ nkọ, ire wo ni nwọn fi owo na ṣe fun ilọsiwaju ilu ati fun ilaju ara wọn to wa lokunkun ? gbogbo nkan ṣa, ayaṣebi Ijọba ba ṣe fun wa. Họwu, kilo kuku ṣe, awa na ko ha gbọdọ ran ara wa lọwọ diẹ kun ?

Gbogbo eyi ti a nsọ dun, kilo njẹ "isọkusọ" iwe irohin ti awọn *Mammy* yi npe ni "*Newspaper pernicious literature*" ti nwọn si ni ki Ijọba ba wọn da duro. Mo ṣebi ẹniti ko ba sa bọti, ko nbẹru ojo. Ju bẹlẹ, ko da ni loju pe nwọn mọ pe ofin irohin kan wa nilẹ yi ti a npe ni "*Newspaper Ordinance*" ti gbogbo oniwe irohin ni lati tẹle. Nitorina, Kilọpo ?

Lakotan, ka tilẹ wipe gbogbo ọrọ ti awọn *Mammy* oniyẹri yi sọ lo tọ suna patapata, sibẹ-sibẹ ko tọ suna ki ọrọ na ti ọdọ wọn lọ sile Gomina, nigbati a ni aṣoju mẹta kọngba-kọngba ni igbimọ Aṣelu, ( *Legislative Council* ) ti a si tun ni **Aṣoju** atata mẹta pẹlu ni igbimọ ti *Municipal.* Ẹnikẹni to ba nfẹ ire ilu yi nitotọ, o ni lati fi nkan-ki-nkan to ba ri han awọn Aṣoju wa, bi bẹkọ, oluware yio bolẹ pirapira.

A gbọ pe Ijọba koi ti f' esi iwe awọn Mammy wa, ṣugbọn niwọn igbati aiye ijọhun ko jọ ti ṣẹhin mọ, a ro lọkan wa pe bi Gomina tabi igbakeji rẹ Ọlọla Donald Cameron ba ka awọn to kọwe na si alaṣeju, ko ni ṣai t' idi wọn bọ omi gbigbona.

*God save the King ! May He also bless Sir Hugh and his administration.*

Emi ni tirẹ nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## Open Letters.

To Celebrities, Notorities, etc., in Different Walks of Life.

### No. 41.

To

His Worship,
The Honourable, C. May, J.P.; M.L.C. (African.)
*Mayor of Sierra Leone,*
Freetown, Sierra Leone.

May it please Your Worship,

This is the very first time in your Honourable career in which all and sundry, at home and abroad, will have the unique opportunity of addressing you as "Your Worship" consequent on your recent elevation to the Mayoral Chair of The Sierra Leone Municipal Corporation ; for this, you have my heartiest congratulations and best wishes.

Those who have been studying you in all phases of public life cannot but be struck with your strong personality, having regard to the zest, the readiness, and no less than the self-abnegation with which you generally always undertake all affairs tending to the welfare of your race and country : your forty year's steady and continuous editorship of The *Sierra Leone Weekly News*, that incomparable West African premier paper, through thick and thin, is a living testimony of your unfeigned patriotism ; surely it does require the heart of a lion to carry on as you have done and are still doing, so thorny, so thankless a task as that of an Editor of a Journal for a milestone such as this, during which friends must have praised, and foes railed at almost every attempt made by you for the amelioration of your people.

But here you are to-day, standing shoulder high in the estimation of both white and black in that progressive peninsular—The Ancient and Loyal Colony of Sierra Leone.

Whilst inditing this letter, methinks I hear those immortal words ringing in my ears :—

"The heights that great men reached and kept,
Were not attained by sudden flights ;
For they, whilst their companions slept,
Were toiling upward all the night."

Yes, whilst others were comfortably ensconced in the arms of Morpheus, and others scoffing at or misrepresenting your movements, you do get busy in trying to do your best for the country, with the result that to-day, you are now become the cynosure of all eyes.

That a prosperous "reign" in the Mayoral Chair be thine is the fervent prayer of your young friend and admirer,

EKO AKETE.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, DECEMBER 1, 1923.

## ỌMỌ-NI-'O-JOGUN.

Owe wa kan sọ pe bi Ẹru ba jọra wọn njẹ ile kanna ni nwọn ti wa; ko dede ti a fi sọ bayi, nitoripe kosi ọja kan to jẹ ti Oyinbo ti nwọn ki nsaba ati ma sọ l'orukọ; fun apẹrẹ, ẹnyin ẹ wo irufẹ iṣana kan ti awọn enia wa onigba-wó-wò-wó (*Petty Traders*) ti nta ri—Iṣana ti a sọ ni Ẹlẹṣin Anabi, ṣe *sea horse* tabi ẹṣin omi ni awọn to ṣe sọ ọ, awa ti a nta sọ ni Ẹṣin Anabi, awọn Oyinbo to ṣe e, sọ ọ ni Kutupa-omi; ẹ ko ri pe ẹmi sisọ ọja l'orukọ jẹ aṣa fun t'oyinbo t'enia dudu?

Ẹwẹ, ọmọ-ni-'o-jogun si jẹ orukọ ti a sọ oriși aṣọ kan ni sãkan nilẹyi; nitorina igbo kanna ni ọdẹ ndẹ; àwọ̀ ati ede lo yatọ, pupa yõ ni ẹjẹ awa mejeji jẹ, bẹ sini ẹjẹ awọn ẹlomiran to mbẹ lode aiye: ki a wa sọ ohun ti o mu ki a sọrọ jijogun ti ọmọ ti a fi soke iwe yi; ninu Iwe Irohin Saro ti a npe ni *Sierra Leone Weekly News* ti ọjọ 10 *November* to kọja, a ri ọrọ kan ka nibẹ to wọ wa lara ṣinṣin, ti a si ro pe yio ji pupọ ninu awọn enia wa giri nibi ati nibi gbogbo ti nwọn ba gbọ; ọrọ na ni pe—ọmọ bibi ọkọnrin kan ti o jẹ ọmọ Ọgbẹni C. May J.P. Ọlọla ti a ṣẹṣẹ yan ni olori awọn Munisipa ti Saro ni lọlọyi de lati Ilu Ọba; enia dudu ni Ọgbẹni na ati ọmọ rẹ ẹniti orukọ rẹ njẹ C. Ọṣọba May; baba rẹ ti ran lọ si *England* fun ọdun pupọ lati kọṣẹ mimọ iwe-titẹ ati iṣẹ Oniwe-irohin ati lati kọgbọn ati iwe pẹlu; o ba ọkọ *German*]ti a npe ni *Waheine* de si Saro ni ọjọ 29 oṣu *October* to kọja gbogbo awọn ẹbi rẹ, obi rẹ, ati awọn ara ilu Saro lo yọ si dide rẹ ni alafia; lai si ani-ani, ifẹ ati ero pe ki ọmọ yi le jogun iṣẹ ti on ti fi lile ni ogoji ọdun nṣe bọ—eyini ni Iṣẹ Iwe Irohin—fun Ilu ati Iran on to jẹ enia dudu ti o si tun nṣe ni lọwọlọwọ yi, lo mu Ọlọla C. May baba ọmọ na lati jẹ ki ọmọ rẹ lọ kọṣẹ kanna ti baba na papa ti fi akoko kan kọ lọd[...] pupọ ri ni Ilu Ọba. Ẹ jẹ ki a bere [...] diẹ lọwọ ara wa; a fi ẹniti o ba nṣete [...] ni yio sọ pe Iran awọn Ọlọla May ti a [...] yi ko la to Ipọsu, ẹni pupọ mọ pe [...] Olowo wa nibi lo jẹ, ana Ọlọla C. J. Geor[...] (Ologbe) ọmọ Ọṣọba. Nigbati Ọgb[...] na si wa bẹ ilẹ yi wo ninu ọdun 1920 awa papa si lo mọ fun ọjọ diẹ ti a ri [...] wọsi rẹ pe ọkọnrin ti a fi nṣepe ọkọnrin, dajudaju ẹniti a bĩre lo jẹ, o si r'ow[...] Ṣugbọn, a koi ti bere ibere na; kiniṣe Ọlọla yi ko ran ọmọ rẹ na ti a wi yi kọ Iṣẹ *Lawyer* tabi ti Dokita tabi Gbagimọlẹ? Ibiti ọrọ gbe sodo si n[...] Ko ha lowo to lati ṣe bẹ ni? Bẹkọ; [...] baba na ni pe ki ọmọ yi le jogun tabi r[...] on ninu iṣẹ on lẹhin igbati ewe bã ti g[...] to ba ti rẹ tan; iru ero yi lo mu ko lọ [...] iṣẹ na, o si jẹ ọmọ onigbọran to gbọ[...] si baba rẹ lẹnu.

Pupọ enia ko ro pe iṣẹ kikọ kan s[...] ni Iwe Irohin ṣiṣe jẹ; kĩṣe ohun ti a [...] binu tabi ki a kanju jalu lojiji, iyẹn [...] Ẹnyin ara, o di melo ni pupọ ninu aw[...] onișowo wa ti nwọn ti pẹhinda ṣe ay[...] nigbati nwọn wa lori ilẹ pe ki awọn ọ[...] wọn le ma ba òwò wọn lọ lẹhin wọn? [...] a ba mu ti Ile Ọṣọba kuro, òwò ẹniti Ọgbẹ[...] Charlie rọpo lẹhin iku baba rẹ, ati aw[...] ọmọ Daddy J. C. Vaughan, ko tun wọ[...] mọ; ti ọrọ õtọ ba de, ki iro salọ; aw[...] Ile òwò awọn baba wa igba-lailai aw[...] isọri-isọri bi Daddy Alade, bi J. S. Leig[...] bi Capt. J. P. L. Davies, bi Z. A. William[...] bi J. J. Thomas, bi Ademuyiwa Haastru[...] bi Daddy Arijẹ, bi John O. George, bi [...] A. King, bi Mabinuori, bi Shitta Be[...] bi "Dr." R. Z. Bailey, bi E. A. Caulcrick, [...] Alẹṣinlọyẹ Williams dà loni? Ewọ ni b[...] tun nri Ile òwò wọn larin wa ki o ma gb[...] siwaju ati siwaju? Dajudaju ẽwọ kọ; ey[...] ohun ibanujẹ gidigidi; o ṣe, o pọ, ọna [...] ohun ọwọ rẹ gbe'lẹ !!!

Nigbawo ni ero a nfi iṣẹ le ọmọ ẹni lọw[...] ma to ye awa enia dudu apa ibi? Ba[...] kọ lo ri lọdọ awọn enia wa ti a tilẹ n[...] ni Saro, awọn ti a nfi ẹ̀wọ̀ pè ni Ajẹ [...]

Bo-nga; (eyini ni gọlugọ) ẹnyin ẹ wo Ile òwò T. J. Sawyerr ti *Freetown* (Saro), ẹniti o iba de'bẹ kole mọ pe Baba olowò na ti ku lọjọ pipẹ ati pe awọn ọmọ ati ọmọ-ọmọ rẹ lo tun 'sogun òwò nã ró titi di oni oloni. Ni ọdun 1921 ni nwọn tẹ Iwe Ika Ọjọ ọṣu ọdun (*Almanack*) ti o jẹ adọta ọdun ti baba wọn ti bẹrẹ titẹ Iwe Oṣu ọdọdun na; a npe Iwe Ika oṣu na ni *Sawyerr's West Africa Almanack* eyini ni Iwe Ika Ọjọ Oṣu Ọdun ti Ilẹ Enia dudu ni Iwọ Òrun *Africa* ti awọn Sawyerr ṣe; ọdọdun lo si njade.

Boya ẹ o tun ma gbọ oruko awọn *Lawyer* nlanla bi Ṣorunkẹ Sawyerr: ara awọn ọmọ Ologbe T. J. Sawyerr ti a wi yi ni nwọn jẹ pẹlu; enia dudu si ni gbogbo wọn patapata. Ọrọ ti a ti nsọ bọ yi, kuro lọrọ yẹpẹrẹ, a ngbọ orukọ oyinbo onişowo nla ilẹ yi ti *John Holt* ti *John Walkden* ti a nri l'arin wa nibi; arọmọ-bọmọ wọn lo ndun nibẹ lẹhin igbati awọn pàpà ti da ina òwò na silẹ lọjọ jọjọ; kiniṣe ti orukọ tabi òwò awa nibi ma nsaba ati tètè ku pi bi ina bẹ? bi enia meji ṣeṣi da òwò tabi iṣẹ pọ, ko ni lọjọ ko ni loṣu ti a o fi gbọ pe nwọn ti ja ajatuka bi ti agba-arin. Ẹ jọwọ ẹnyin ara, ẹ f'oju agba yẹ gbogbo ọrọ ti a ti nsọ bọ yi wọ, ohun ribiribi ni a mọ si larin wa.

Igba l'aṣọ, Igba l'ẹwu,
A w'aiye ma ni'gba
Dabi eṣinşin ku s'oju ọti.

O dọwọ nyin o, a-mu lele, ọpa a-gbelaka t'ẹhin lo ma ju o ! ! !

---

## IPADE TO LARINRIN.

Gẹgẹ bi a ti sọ tẹlẹ, a ṣe Ipade kan ti o wọ to gbajẹ ni Ile Afari Ogun l'Ẹhingbẹti ni *Monday* osẹ yi, awon ti o wa joju; gẹrẹ bi agogo marun ti lu, bẹni Ọgbẹni Adeloye Ṣolankẹ, okunrin jẹjẹ abija kunkun ẹniti a ti sọ fun tẹlẹ, fi gbolohun ọrọ meji tabi mẹta ki Alaga Ipade na Ọgbẹni J. A. Oṣodi; o si pe e ki o joko sipo rẹ; bi Ọgbẹni wa yi ti kuku dide lati bọ si ori aga, bẹni oio atẹwọ rọ fun inu didun ti awọn to wa si Ipade na ni si.

Lẹhin eyi, a pe *Editor Eko Akete* ki o rohin bi iṣẹ Iwe Irohin rẹ na ti nlọ si; Ọgbẹni yi si dide o si mu ọrọ lati igbati a ti pe lati oke wa ki o bẹrẹ si iṣẹ na ti o di ọmọ oṣu mẹdogun nisisiyi; o sọ pe on bẹrẹ si nipa titẹ Igba (200) Iwe Irohin na lọsọsẹ, o si wipe loni, iye ti on ntẹ lọsọsẹ jẹ Ẹgbẹrun (1000) o sọ ti inira to wa fun nipa ti owo ati ma ba iṣẹ na lọ, o si dupẹ pupọ lọwọ awọn bi Alaga na, bi Ọgbẹni B. C. Vaughan bi Alhaji Abuduramọnu Davies, bi Ọgbẹni D. B. Ọṣuntolu, bi Ọgbẹni Alfred Williams, bi Ọgbẹni Ṣolade ati bi Mrs Akinyẹmi ati awọn Jakanjakan miran ti nwọn nsan owo gbigba Iwe Irohin na dede nigbati a ba ke si wọn; o sọ pe laisi Ipolowo ọja ninu Iwe Irohin ko si Iwe Irohin kan ti o le gbe iṣẹ na d'ori.

O mu Apẹrẹ Iwe Irohin *West Africa* kan han awọn enia o si ṣi opọlọpọ Ewe Iwe Irohin na ti o jẹ okuru Ipolowo-ọja; o sọ pe nipa eyi, o rọ *Editor West Africa* lọrun lati ma ba iṣẹ na lọ laisi idawọkọ kan. O ke si awọn enia fun iranwọ; lẹhin eyi o joko pẹlu atẹwọ ti a fi yẹ Irohin rẹ na si.

Nigbati o ṣe, Alaga sọ pe ki awọn to wa sibẹ sọ si ọrọ ti a mu wa siwaju Ipade na.

Ọgbẹni Alfred Williams ti Ile owo C, W. S ni ilẹ yi si daba pe ki *Editor Eko Akete* gbe iwe sita fun irufẹ iranwọ bẹ, o ni on papa yio san ṣokoto giri lati ran lọwọ.

Ọgbẹni E. A Oluyẹle Bright olori Akọwe ni'le Iṣẹ ọkọ ilẹ ni Ebute Mẹta, si dide gbe lẹsẹ; o sọ pe o jẹ ohun itiju fun awọn ẹlomiran ninu awọn olowo wa lati ma sa sẹhin ni nini ọwọ si ohun rere fun ilu bayi nipa iwa anikanjọpọn-wọn; o sọ pe lati igbati "Eko Akete" yi ti di tiẹ kakiri, ọgọrọ ni on ri ti nwọn ki jafara ati ma ka ni akagbadun.

Iya Afin Mrs. Benedicta Akinyẹmi olori awọn olukọ Obinrin ni Ile Iwe Alapako (*St. Peter's School*) sọrọ ti o ka ni lara nipa ti awọn ẹlomiran ti nwọn ko nnani ede wa, ani ede Yoruba, o sọ ti ohun kan ti on ri ka ninu *West Africa* ti *April* 14 ọdun ni, nipa yẹyẹ ti awọn oyinbo kan nfi awon ara wa to jẹ Ara Saro ṣe fun si-segedehun ni ede Gẹsi ti awọn ara Saro nṣe lalai mọ A. B. D to wa lẹsẹ Malu ninu ede iya wọn; o tẹnumọ fifi ede Yoruba wa yi kọ awọn ọmọ wa daradara ki a ma ba jẹ alaigbede ninu ede wa ti a ngberaga lati sọ lẹnu, ṣugbọn ti ko le ka a ninu Iwe.

Ọgbẹni Ṣolade ti Ile Ẹro Itẹwe ti Ijoba li Eko sọ pe on yọ pupọ lati wa si ipade iyebiye yi, o si ṣeleri ati sa ipa rẹ fun ati tu owo jọ fun lilọsiwaju Iwe Irohin na; o si daba pe ki *Editor* fi apọ iwe sita fun awnọ enia.

Ọgbẹni D. Ayọdele Bright Akawe ni Ile Itẹwe ti *Railway* Ebute Mẹta, sọ ti inira ti o wa fun şişe Iwe Irohin; o si sọ ti awọn "oku onigbese" miran ti nwọn nfẹ lati ma gba Iwe Irohin, ṣugbọn ti o ma ndi akatakiti fun nwọn lati sanwo rẹ. O

si sọ ti Oyinbo Ọlọla kan ti a npe ni *Lord* Rothermere ni Ilu Gẹsi ti o ra orişirişi Iwe Irohin bi mẹta tabi mẹrin ni Ọdunrun Ọkẹ owo pound (£6,000,000) o s ọ ti awọn enia wa bi Hutton Mills ni Ilu Aganyin ati J. A. Sarbah ti nwon ti şe iranlọwọ fun Iwe Irohin Ilu wọn ni *Accra* ati ni *Cape Coast*; o si gba Ipade nimọran lati ran "Eko Akete" lọwọ.

Ọgbẹni D. B. Ọşuntolu ti Ile Owo Miller Brothers so pe o dun on diẹ pe eto ko pọ to bi a ti ro si, şugbọn o tun sọ pe Sura nkan ni ka ma wo ki şe pupọ lai le şe ohunkohun (*Quality not Quantity*) o kirin Mrs. Akiyẹmi lẹhin pe o yẹ ki a tubọ gbe ede Ilu wa ga; o si sọ titankalẹ Iwe Irohin *Eko Akete* na, o si jẹjẹ íranwọ rẹ.

Ọgbẹni Alẹşinloyẹ Williams onişowo sọ pe on ti gbọ ọrọ to, ati pe ki a bẹrẹ mu'şẹ şe loku warawere o ni on ya 10/- sinu apo Iranlọwọ *Eko Akete* na; awọn toku si tẹle ẹ. A fi owo na si isalẹ Iwe Irohin yi.

Lẹhin eyi ni Alaga sọrọ iwuri lọpọlọpọ, o sọ ti ayan awọn *Editor* Igbani ati pe a le fi işẹ Iwe-Irohin şişe we Işẹ Alufa ti o jẹ işẹ ti ko lọpẹ; o sọ ewu to wa ki a tilẹ ni awọn olowo kan dawo jọ latiİgba *Editor* kan lati ma şe işẹ Iwe Irohin, o ni *Editor* na, ko ni gbodo sọ ti inu rẹ tara lalai gbun awọn Alafẹhinti rẹ yi; o sọ pe on şakiyesi pe lati igbati on ti nka *Eko Akete* Yoruba inu rẹ ti o jẹ ojulowo ti on ko ba pade ninu Iwe yoruba miran ri ni on nri nibẹ; o sọ ti ọpọlọpọ enia ti nwọn sure kọ A. B. D. wọn nisisiyi lati fi tete mọ Iwe Irohin Yoruba ka; o sọ pe eyi fihan gbangba pe oyinmọmọ to wa ninu ede wa kuro ni diẹ; o si sọ pe ki *Editor Eko Akete* ma fi inu kan şe işẹ rẹ ati otitọ inu; o ni ti o ba nşe eyi, ko ni si kuku fun ilọsiwaju Iwe Irohin na.

Alaga na si fi £1 1s. si apo owo Iranlọwọ *Eko Akete* na.

| | | |
|---|---|---|
| Ọgbẹni | J. Alẹşinlọyẹ Williams | 10/- |
| ,, | Alfred Williams | 10/- |
| ,, | C. A. King | 10/- |
| ,, | A. W. Olukolu | 10/- |
| | Şolade | 10/- |
| | Mrs. Benedicta Akiyẹmi | 5/-. |

Diẹ ninu awọn to tun wa ni Ọgbẹni A. Ibaru, Ọgbẹni S. A. Thomas, Ọgbẹni C. L. E. Silva ati awọn miran.

A nreti awọn enia wa to ku ni'le, l'oko, tabi l'ajo ki nwọn maşai dabira ti wọn pẹlu. A o ma jihin owo-kowo ti a ba rigba sinu Iwe Irohin yi lọsọsẹ. Ki Baba gb'ọwọ gbogbo wa. Aşẹ!!!

## Ẹ GBA AWỌN ORIN CHRISTMAS LA

A ki nyin o,

Gbogbo awọn ẹniti nşe akiyesi gẹgẹ bi papa ti nfi ibaralẹ wo bi a ti nşe aisun Iwọ Christmas si lati ẹnu odun diẹ wọnyi wa, ko şai ma fi itara ronu wipe, kini yio tilẹ gbe awọn orin Christmas wa yi li ẹhin ọia.

Ohun ti mo ntọka si ni iru ọna aibikita ti a nkọ awọn orin daradara ati orin ti ko li wọnyi, a nba a jẹ, a sọ ọ di orin ijo ati bi idaraya lasan.

Ko si ohun ti o dara bi ki enia ma gbọ orin Christmas ti a nkọ daradara, ati tọwọtọ tabi ti a ntẹ duru si, ti awọn agbajọ enia ba lati kọ nigbati ọwọ pa ti ẹsẹ pa ni oru aisun Christmas, iru orin bayi:—

O de ni arin ọganjọ,
Orin ologo ti igba lailai ni;
Lati ọdọ awọn angẹli ti nwọn bẹrẹ
[si tosi aiye.
Lati f'ọwọ kan *harp* wura wọn:
Alafia li aiye, ifẹ rere si enia,
Lati ọdọ Oba Olōre-ọfẹ l'ọrun.

*Aiye si farabalẹ ni idakẹjẹ,*
*Lati gbọ orin ti awọn angẹli nkọ.*

Nitotọ ni, awọn orin ti a ma ngbọ nigba dabi orin awọn angẹli gān; şugbọn ni sa isisiyi o dabi igbati eşu iba ma kọ orin yẹyẹ.

Iru awọn ti nwọn si nda nkan wọnyi silẹ pataki ni awọn ti nwọn şẹşẹ ndi Onigbagbọ ni il gbogbo ti awọn Onigbagbọ ba wa, awọn en wọnyi ni èro rere, şugbọn ko ye wọn ju bẹ lọ. si şe èro mi lati da wọn li ẹbi pupoju, tabi ki ọro ti ko wọ fun wọn; şugbọn tọkantọkan ni fi bẹ gbogbo ẹnyin Alufa wa, gbogbo ẹnyin Oni Ọlọrun ati ẹnyin Oloye ninu ẹgbẹ Ọmọ-o Igbala, ati ẹnyin ti ohùn nyin to ilẹ li arin wọ ati ẹnyin ti ẹ mọ ọna ti ẹ le fi tọ wọn, ki ẹ si şe atunşe wọn pẹlu.

Mo si bẹ iwọ Oni 'we-irohin yi pẹlu, ki o ba ni li ohùn si ọrọ ti a nkilọ rẹ yi lati inu iw irohin rẹ wa.

Koi ti buru ju de ibi wipe ko şe şe mọ, ah ko ba mura. Kaka ti a ba ma ni ireti lati awọn orin didun wọnyi ni akọtun ninu Isin ow Christmas, a-gbọ-sú ti a ti gbọ ọ ni gbogbo or jẹ ki o tun ni adun mọ.

Ẹ jẹ ki a ranti wipe, bi a ba şe bayi fọ aw orin na, ko si omiran ti a o fi rọpo wọn o ibiti a si ngbadun julọ ninu Isin Christmas yi sọnu gbe patapata.

Ibâṣe akanṣe orin Christmas, (ANTHEMS) ni o, abi eyiti nwọn npẹ ni Kántatà, (CANTATA) bi o ti wu ki nwọn dun to, nwọn ko le rọpo awọn orin i o rọrun, ani orin ẹmi wọnyi; nitorina, gbogbo nyin ni mo bẹ tọkantọkan wipe,—

Ẹ ma ṣe jẹ ki awọn orin Christmas ṣegbe o.

T. K. E. PHILLIPS.

## "EKO AKETE" THE PEOPLE'S PAPER.

We have much pleasure to announce that the present circulation of our weekly Newspaper *Eko Akete* is 1,000 copies weekly: these copies are easily disposed of with the possible exception of few ones kept for Office File and these in turn are being hunted for by others who are unfortunate enough to be behind time in buying their own copies.

To the best of our knowledge and belief, we know of no other weekly journal in Lagos, or anywhere in Nigeria for that matter, to beat this record.

Will intending Advertisers please note?

## ALAYỌNUSỌ, TIRẸ TI JẸ? TIRẸ TI RI?

A ṣe kilọ-kilọ yi fun *Editor* "*Eleti Ofe*" ki o maṣe lọwọ si ọrọ ti ko kan lọwọ ti ko kan lẹsẹ gẹgẹ bi a ti ri ti o ṣe siwa ninu Iwe-Irohin rẹ ti ọsẹ yi. Ẹni-Ọwọ ti *Editor* yi nitori rẹ pa ara rẹ lopo si ti wa ki wa ni *Wednesday* (Alaruba) ọsẹ yi, a si jẹwọ-jẹwọ titi; niwọn igbati o wa ni *office* wa fun ọgbọn iṣẹju ko ṣeṣi mi ringindin pe a ṣe laifi kan si on nitori ohun ti *Editor* yi nfi ọwọ ja nu si yi; ki a tilẹ wipe boya itiju lọ mu lati ma ba wa sọ nigbati Ẹni-Ọwọ na wa ki wa, ibati kọwe si wa ṣiwaju nipa ọrọ na; nigbati kosi ṣe ikan ninu mejeji, kini ẹkun ti awọn agbodegba wọnyi nsun kiri? Họwu! Ọgbẹni *Editor* "*Eleti Ofe*" ti yara gbagbe ori to lọ fi jona ni koi pẹ yi lọdọ Oyinbo Ọgbẹni Mulford ki o to gborun ara rẹ? A tunṣe Ikilọ yi fun, ki o maṣe ku sori ọrọ-ọlọrọ bi obi.

## Thanks for Sympathy.

Mr. Shafi B. Vintura agent for C. F. Hutchinson & Co., Lagos, begs to return his sincerest thanks to all who, by personal calls, telegrams, letters, and otherwise, have sympathized with him in the death of his brother Jubirila's wife, ALIMOTU ALAKE (of Mogaji Court Epẹtẹdo) which took place at Lagos on Thursday morning the 15th November 1923.

## CHANGE OF NAME.

From and after the 1st January 1924, I, THEOPHILUS ABIMBOLA PHILLIPS, of 72, Okepopo Street, Lagos, and Railway Printing Office, Ebute Meta, desire to be known and addressed by my ancestral name

ABIMBOLA BANKEFA-OJOMU

all documents letters, correspondence and agreement signed THEOPHILUS ABIMBOLA PHILLIPS by me prior to this date remain valid. Dated by me this 28th day of November, 1923.

T. A. PHILLIPS

## NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

LAWANI BAMGBADE LAYENI,

(Deceased.)

*Pursuant to the Statute 22 & 23 Victoria, Chap 35.*

NOTICE IS HEREBY GIVEN that all creditors and other persons having any debts, claims or demands upon or against the estate of LAWANI BAMGBADE LAYENI, late of No. 75, Broad Street, Lagos, Nigeria, who died on the 4th day of September 1921, intestate, and Letters of administration of whose personal property were granted by the Supreme Court of Nigeria to us the undersigned, are hereby required to send in particulars of their debts, claims or demands in writing to us at 4, Layeni Street, in Lagos, aforesaid on or before the 31st day of January 1924, after which day we will proceed to administer the estate and distribute the assets of the said deceased amongst the persons entitled thereto, having regard only to the claims and demands of which we shall then had notice and that we will not be liable for the assets of the said deceased or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose claim or demand we shall not then have had notice.

And all persons indebted to the said estate are hereby required to make immediate settlement of their account.

Dated at Lagos, this 24th day of October, 1923.

AKIN: ADESIGBIN,
IMORU LAYENI,
*Administrators.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. ( MORNING )

Masses Isin Arọ,
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ( Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's ( Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rt. Rev. Bp. I. Oluwọle ( In charge ) |
| 6.30 p.m. | | |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's ( Jordan ) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | ,, do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | ,, D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | ,, E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | ,, F. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | ,, S. A. Pearce |
| 10.30 a.m. | Obun Eko | do. |
| 7 p.m. | do | Bro. J. S. Benjamin |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | ,, G. A. Oke |
| 9 a.m. | Erelu | do. |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Laleyẹ |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akiuọla |
| 6.30 p.m. | | Bro. J. B. Coker |
| 9 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. J. O. Oyekunle |
| 4.30 p.m. | do. | Bro. T. J. A. Green |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. S. M. Phillips |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi ( Baptist ) | Bro. E. A. Ojo |
| 6 p.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. A. Oshodi |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

**BROTHERHOOD**

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Respct'ble Bro. J. Kọṣiji Turton |
| 7 p.m. | | Prof. Adeoye Deniga |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service I. A. Shitta |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe ( Bamgboṣe Street. ) |

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon , Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

| | |
|---|---|
| 10 a.m. | Capt. A. A. da Costa |
| 7 p.m. | do. |

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS—EKURO.**

Bi awọn oyinbo ile-ọwọ wọnyi ti gba Ọja *( Produce )* l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya ( Niger Co.) G. B. Ollivant, Oyinbo Agbẹra ( Lagos Stores ) MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product.

£13 10s. £14 fun *ton* kan

EPO.

£24 10s. £26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£14—£19 fun *ton* kan bakanna.

**KANO—COMPETITIVE PRICES**

Ground Nut—£13 17s. 6d. per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

PRICES ON APPLICATION.

TO

S. I. M. Johnson,

9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

**Wool, Wool, Wool.**
**Silk, Silk, Silk.**

Wulu tabi Siliki lo nfẹ ra ọmọ iya mi? Lọ si Ṣabu Iya Labu, nibẹ ni iwọ yio ri ni orişipe, Wulu ati Siliki lo fi şişẹ şe—Kọbọ ẹru.

(Abulati mbẹ pẹlu bi tẹdi, ọmọ iya Siliki ni.)

18 & 137, Victoria Street.

ẸNIKẸJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

FOR SALE

One upright grand Iron-frame Piano, with beautiful tone. New condition—Owner going on leave, and will repurchase on his return six months.

For Terms, etc., apply to the Editor.

**The Union Night School.**

Founded Jan. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor).

For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati ọşişẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati şe idanwo fun işẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nşe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday, Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* (Loke.)

TO LET.

A House with one Passage, Parlour, and Room, two extra Rooms and passage with Kitchen and Bathroom and a large space in the backyard at 14 Alof Street; suitable for those seeking Rest and Quiet. For Terms apply to :—Mukitalabi Allah, 14 Ajanaku Street Lagos or 4 Ereko Street Lagos.

***Authority.***

I, the undersigned do hereby require the Editor of *Eko Akete* to announce the sale of my Cinema the description of which is as follows :—

(A Vendre) Description in full.

Un appareil Cinema Marque "Pathe Frere" état neuf.

Un groupe électrogène Marque "Faster" Comprenant :

Un Moteur à éssence Force 5 h.p.

Une Dynamo de 45 Ampères 70 volts.

S'adresser à Mr. Radji Emmanuel,
Commerçant à Porto-Novo,
(Dahomey.)

# A. KESSLER,

7, Labinjọ Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
The German Trading House,
Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine, as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Descent Wristlet Watches. sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite

CHAMPAGNE per case £3. 5. 0.

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless varie[ty] at 50, Dosunmu Street, Lagos,

**Prices to suit everybody.**

*Call now, fortune awaits you.*

## OGUN YANMUYANMU ATI EṢINṢIN.

(*Fly Catcher.*)

Eṣe ti o fi nję ki Yanmuyanmu ati Eṣinṣin ko arun ba ọ, nigbati ogun rẹ wa ni arọwọto rẹ. Ẹgbẹrun pere ni (3d) Ẹdẹgbarun fun mejila (2/3d a dozen.)

A si ni ipari olorun amu irun daradara, o si ma nję ki irun sunmọlẹ, nję ki o ma kọmọna bi jigin, ari malelọ ati pada ẹhin. (*Hair preparations.*)

Kọwe tabi bere fọdọ

DIPO TUNDE & Co.,
P.O. Box 335,
30, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja ninu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ko.

*Ibi ni ẹnyin ro si mi—Ṣugbọn Oluwa mọ si rere*

## ỌKANLAWỌN BALOGUN BROTHERS

Dealers in best quality of Produce viz:—Cocoa, Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc., etc.

*Head Office:*—16, BANKOLE STREET, LAGOS.

*Branches at:*—Lagos, Agege, Agbado, Ijo, Ilora, Wasinmi, Owowo, Ibara, Lalenwa, Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun and Oshogbo.

*A trial order will be thankfully solicited.*

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LICENSEE.